# IṢẸ-IRANṢẸ PAULU NI MẸLITA ATI ROMU

**Iṣe Awọn Apọsteli 27:1-44; 28:1-31**

**ẸKỌ 371 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ẹ lọ si gbogbo aiye, ki ẹ si ma wasu ihinrere fun gbogbo ẹda" (Marku 16:15).**

### Titan Ihinrere Kalẹ

Ọkan ninu aniyan ọkàn Paulu ti o ga ju lọ ni o n bá lọ yii – o n lọ si Romu. Eyi ki i ṣe irin-ajo idẹra. Ninu iroyin ti Paulu ṣe nipa irin-ajo rẹ, kò sọ nipa bi okun ti dara, ilu, oke tabi ayika oko. O n ri awọn nnkan ti o ju eyi ti oju rẹ n bá pade. O n ri nnkan ti o gba ero ati ayé rẹ kan, ti o rú itara ọkàn rẹ soke, ti o si n ṣakoso iṣisẹ rẹ kọọkan. O ri awọn ọkàn ti n ṣegbe; o wa laaye ki o ba le waasu Ihinrere fun wọn.

Ẹ jẹ ki a kọ ẹ̀kọ ninu igbesi-ayé Paulu pe a kò wa laaye lati gba ibukun nikan. A n jẹ adun awọn ibukun Oluwa, ṣugbọn a ni lati jẹ́ ibukun fun awọn ẹlomiran. Bi akoko kan ba wà ti Oluwa n fẹ ọkunrin, obinrin, ọmọkunrin ati ọmọbinrin ti wọn n fẹ sin Oluwa ati awọn arákunrin wọn, ọjọ oni ni. Gẹgẹ bi ohun ti o ṣẹlẹ ninu Bibeli nigba lailai, "Ipe Makedonia" – "Rekọja wá … ki o si ran wa lọwọ," n dún kikankikan (Iṣe Awọn Apọsteli 16:9). Bi awa kò tilẹ le jade lọ si ilẹ okeere, a le gbadura fun awọn ọkàn ti n ṣegbe ati fun awọn ti o le jade lọ lati kede Ihinrere.

### Ewu Oju Omi

Igba o le mẹrindinlọgọrin eniyan ni o wà ninu ọkọ̀ oju-omi naa ki o to ṣi. Ki i ṣe ọkọ̀ ti o le sare pupọ bi iru eyi ti a n lò lọjọ oni, ṣugbọn ọkọ̀ igbokun ti lailai ti o kun fun awọn nnkan to wuwo bi okùn ati awọn irin ti o gbe igbokun duro, ọkà ati awọn nnkan èlo inu ọkọ. Nitori ewu nla ti igbi okun ati ikudu ọjọ yoo fà, Paulu kilọ fun ọlọkọ pe ki o jẹ ki wọn duro ni ebute Krete (Iṣe Awọn Apọsteli 27:21). Ṣugbọn ọga ọkọ kò feti si ikilọ naa, nisisiyii o dabi ẹni pe ireti kò si mọ; fun ọjọ pupọ ni wọn kò ri oorun tabi irawọ bẹẹ ni igbi nlanla si n bì lu ọkọ. Nigba ti gbogbo ireti a ti là dopin, Paulu mu awọn ero inu ọkọ̀ lọkàn le nigba ti o sọ fun wọn pe angẹli Ọlọrun duro ti oun ni oru o si sọ pe, "Má bẹ̀ru, Paulu."

### Igboya Paulu

Eyi jẹ akọsilẹ pataki ti a ni lati kiyesi nipa pe ki eniyan Ọlọrun wà laaarin awọn eniyan ni akoko ewu ati ijamba. Paulu jẹ apẹẹrẹ igbagbọ́ ati igboya ninu idanwo kikoro. O mu awọn eniyan ni ọkàn le pe gbogbo wọn ni a o dá sí. Lati ọwọ Oluwa ni a ti dari wọn si erekuṣu kekere ti a n pe ni Mẹlita. (Erekuṣu yii jẹ ọkan ninu awọn ibi ti a rọ́ àgbá si ju lọ ninu Ogun Agbaye Keji.)

Bi awọn atukọ ti fẹ bẹ́ sinu omi lati wẹ lọ si ebute Paulu wi fun wọn pe, "Bikoṣepe awọn wọnyi ba duro ninu ọkọ̀ ẹnyin kì yio le là." O tun rọ wọn lati jẹun lẹyin aawẹ ọsẹ meji ti wọn ti gbà. Bi ọkọ ti n lọ siwa-sẹyin, ni Paulu n waasu Ihinrere fun awọn eniyan ti o wà ninu ogbologbo ọkọ igbokun naa.

### Ọkọ Ihinrere

Ni ọjọ oni, awa paapaa dabi ẹni ti o wà ninu ọkọ ti a n pè ni "Ọkọ Rere Sioni." Nigba miiran a maa n wà ninu ìjì lile; òkun igbesi-ayé si maa n le nigba pupọ. Ṣugbọn bi a ba ti wà ninu ọkọ̀, má ṣe jẹ ki a "fi ọkọ naa silẹ." Oun nikan ni ọkọ̀ ti yoo bori gbogbo ìji; gbogbo awọn ti o kù yoo rì. Ṣugbọn ọkọ Ihinrere yoo fó ni alaafia titi yoo fi gunlẹ si Ebute Ọrun.

Eyi rán wa leti ọ̀rọ ti o larinrin ti James Lawrence Ọga ọkọ ninu ogun ọdun 1812 sọ bi o ti wa loju ikú ninu ọkọ ogun. Awọn ọ̀rọ rẹ ikẹyin fun awọn oṣiṣẹ rẹ ni, "Ẹ maṣe fi ọkọ yii silẹ."

### Gbogbo Wọn Gunlẹ si Ebute

Gbogbo awọn eniyan naa ni o gunlẹ ni alaafia bi o tilẹ jẹ pe ìgbi fọ́ ọkọ̀ naa si wẹ́wẹ. Awọn olugbe erekuṣu Mẹlita fi aanu hàn fun awọn ero inu ọkọ̀ ti aarẹ mu ti otutu n pa, wọn si dá iná fun wọn. Bi Paulu ti n ṣe iranwọ lati ṣa igi idana jọ, ejò paramọlẹ kan lọ́ mọ ọ lọwọ ṣugbọn o gbọn ọn ju sinu iná lai

ni ipalara. Awọn ara ilu na n woye pe ọwọ́ rẹ̀ fẹrẹ wú tabi pe yoo tilẹ ṣubu lulẹ ni okú. Ṣugbọn lẹyin igba pipẹ wọn ri i pe ibi kan ko ṣẹlẹ si Paulu. A ni idaniloju pe Oluwa ni O pa a mọ lọwọ ipalara.

### Iṣẹ Itankalẹ Ihinrere ni Erekuṣu naa

Nigba gbogbo ni Paulu maa n lo anfaani ti o ba ni lati waasu Ihinrere fun ẹnikẹni ti o ba pade. Publiu, ọkunrin ọlọla erekuṣu naa ṣoore fun Paulu ati awọn èro inu ọkọ̀. Nigba ti ara baba ijoye naa si ṣe alaidá, Paulu gbe ọwọ́ le e, o gbadura, a si mu un lara da. Awọn miiran ti wọn ni ailera pẹlu wá sọdọ Paulu Oluwa si mu wọn ni ara da. "Ami wọnyi ni yio si ma ba awọn ti o gbagbọ́ lọ; Li orukọ mi ni nwọn o ma lé awọn ẹmi èṣu jade; … nwọn o gbé ọwọ́ le awọn olokunrun, ara wọn ó da" (Marku 16:17, 18).

### Ẹ̀kọ́ Paulu

A yan Paulu ati awọn Apọsteli ti o kù lati Ọrun wá lati waasu Ihinrere. "Nwọn si jade lọ, nwọn si nwasù nibigbogbo, Oluwa si mba wọn ṣiṣẹ, o si nfi idi ọ̀rọ na kalẹ, nipa àmi ti ntẹ̀le e" (Marku 16:20). A fun wọn ni awọn iwe ẹri lati ọwọ́ "Ọgagun patapata," ani Ọlọrun tikara Rẹ̀. Ẹkọ jẹ ohun ti o dara lati ni, ṣugbọn eyi ti o dara ju ni "kikọ́ ẹ̀kọ́" lati inu Ọrọ Ọlọrun ati gbigba adura pupọ. Paulu ti ṣiṣẹ aṣekara ni ile-ẹ̀kọ́, o si ti kọ́ ohun pupọ lati ọwọ́ awọn olukọ rẹ̀, ṣugbọn lati ọjọ ti o ti bá Jesu pade ni Ọna Damasku, ni o ti ni Olukọ titun. Lati ọwọ́ Rẹ̀ o kọ́ ẹ̀kọ́ ti o ga jù. Ni ọdọ Rẹ̀, awa pẹlu le kọ́ ẹ̀kọ́ nipa ọ̀na ododo ati iwa-mimọ́. Ẹ jẹ ki a tẹra mọ́ ẹ̀kọ́ kikọ́ ni "ile-ẹ̀kọ́" yii.

### Itẹsiwaju si Romu

Lẹyin oṣu mẹta ni erekuṣu naa wọn mura lati ṣikọ. Awọn eniyan ibẹ fun wọn ni awọn ohun ti wọn ni lati lo fun irin-ajo wọn ti o kù.

Nikẹyin wọn dé Romu ilu nla nì, olu-ilu gbogbo agbaye ni igba naa. Paulu ṣe alaye fun awọn Ju ti o wà ni Romu bi oun ṣe wá si ibẹ gẹgẹ bi onde. O sọ fun wọn nipa Jesu lati owurọ titi di aṣalẹ. Awọn kan gbagbọ́ ṣugbọn awọn miiran kò gbagbọ́. Fun ọdun meji ni o fi n waasù fun awọn eniyan nibẹ, ṣugbọn nitori aigbagbọ́ wọn, o sọ fun awọn Ju pe Ọlọrun n rán ihin igbala naa si awọn Keferi ti yoo gba a.

### Anfaani Wa

Lọjọ oni awa ti a jẹ Keferi ti gbọ́ nipa itan Ihinrere: igbala kuro ninu ẹ̀ṣẹ, nipa Ẹjẹ Jesu; isọdimimọ́, ọkàn mimọ́, nipa Ẹjẹ Rẹ̀ bakan naa, fifi Ẹmi Mimọ́ wọ ọkàn ti a ti sọ di mimọ́; iwosan nipa agbara Ọlọrun ati awọn ibukun miiran ti a maa n ri gba lati ọwọ Oluwa.

Ẹ má ṣe jẹ ki a dabi ọ̀pọlọpọ awọn Ju ti ọjọ Paulu; wọn gbọ́, ṣugbọn oye kò ye wọn nitori pe "eti" inu wọn di; wọn ri, ṣugbọn wọn kò mọ oye, nitori pe oju ẹmi wọn fọ́. Ẹ jẹ ki a ṣi ọkàn wa payá ki a si ni ipinnu ti o daju pe bi ọ̀na si Ọrun kò tilẹ rọrun, a o fi ara da gbogbo nnkan lile, gẹgẹ bi Paulu, a o si pari ire-ije wa, nipa oore-ọfẹ Ọlọrun.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti irin-ajo oju-omi fi lewu ni akoko wọnni?

2 Ki ni imọran Paulu? Njẹ a gbà a?

3 Ki ni ṣẹlẹ ti o fun Paulu ni igboya? Bawo ni o ṣe mu awọn ẹlomiran ni ọkàn le?

4 Bawo ni wọn ti gbaawẹ tó?

5 Eniyan meloo ni o wà ninu ọkọ̀?

6 Bawo ni wọn ṣe gunlẹ? Ẹnikẹni ha ṣegbe bi?

7 Ki ni orukọ erekuṣu naa?

8 Njẹ awọn eniyan bá awọn ero ọkọ naa rẹ́? Sọ ohun ti wọn ṣe.

9 Ki ni Paulu ṣe ni akoko ti o fi wà nibẹ?

10 Njẹ awọn eniyan ni Romu gbà Ihinrere?